

# • Agbejade Ifenuko

# Ajo Isokan Orile - Ede Agbaye

# Lodun Milinionu

## • "Awa Eniyan..."

IPADE MILINIONU
NEW YORK, 6-8 SEPTEMBER, 20



A Translation of "The Millennium Declaration" Into Yoruba

# 1

## AGBEJADE IFENUKO

## AJO ISOKAN ORILE - EDE AGBAYE

## LODUN MILINIONU

IPADE MILINIONU
*NEW YORK, 6-8 SEPTEMBER, 2000*

## ORO ISAAJU

Agbejade ipinnu Ajo Isokan awon Orile-Ede Agbaye lodun Milinionu yii je gbongbo aseyori kan ninu senturi tuntun ti a wa yii. Nibi ijoko ipade Milinionu ti o waye lati ojo kefa si ojo kejo osu kesan odun 2000 ni Ilu New York won ti fowo si agbejade naa. Agbejade yii je ipinnu atokan wa awon Asiwaju Ijoba meta-din-laadojo pelu awon orile-ede mokan-le-laadowa lapapo, gbogbo won ti won kopa nibi ipade awon Asiwaju lagbaye, eyi ti o bu yaari julo.

Agbejade naa je abajade ijiroro, ifenuko ati ifikunlukun ti o waye laarin osu melo kan nibi ti won ti faye gba awon eniyan ni elekun-je-kun lati so ero okan won. Koda agbo ipade Milinionu yii fi aaye gba ki awon eniyan jade so ero okan won.

Inu mi dun gidi-gidi lati rii pe opo lara awon aba lori ohun ti a n lepa ati awon ojuse wa ti mo da ninu ijabo mi fun odun Milinionu ni o jeyo ninu ipade naa.

Ero okan mi ti mo fi daba ipade ajodun Milinionu je ona kan lati fi le jeki awon ohun edun okan eniyan kookan nibi-kibi kojo-po lati wa ojutu si lasiko Milinionu yii. Bi mo se n teti si oro iyanju lati enu awon Asiwaju lagbaye ti mo si tun ka awon agbejade ifenuko ti won fowosi, je ohun iwuri furi mi lopolopo lori ise ti o wa niwaju wa pelu emi akin ti awon Asiwaju yii fi kobi ara si imusese lori awon nnkan wonyii.

Awon Asiwaju yii ti gbaradi lati musese lori adinku si idaji ogooro awon eniyan ti ise n ba ja ati lati pese omi ti o mo gaara pelu eto eko ti o ye kooro fun gbogbo gboo lawujo. Ki won si gbogun ti arun Eedi (HIV/AIDS) pelu sise ise idagba soke lakotun.

Won ti beere fun afikun iyanju Ajo-Isokan Agbaye lorii wiwa alaafia, ki awon eniyan lawujo fi le ni igbekele lori ninu lasiko

irukerudo. Bakanna ni awon Asiwaju yii tun ti beere fun gbigbogun ti iwa irenije, aisedajo ododo, tembelekun, iwa ijegaba lori eni ati odaran lawujo. Ki a si se idaabobo lori awon ohun ajogunba wa tii se ile aye fun ojo iwaju awon iran ti o n bo.

Ninu agbejade yii, awon Asiwaju lagbaye ti fi ohun sokan lati gbaruku ti Ajo Isokan Agbaye ni senturi tuntun yii. O ti je won logun bayii lati se abojuto ojuse Ajo Isokan Agbaye. Won n fe se akitiyan paa-paa julo lati se aseyori. Fun ipa ti emi, mo ti ju ara mi sile pelu awon osise mi lati gbaruku ti agbejade awon Asiwaju yii. Sugbon lai siyemeji awon Olori wonyii gan-an ni a le pe ni Ajo Isokan Agbaye. Owo won ni ida ati agbara wa, nitori naa ojuse won ni lati se aseyori awon ilana ti won gbe kale gege bii agbejade. Si gbogbo won ati agbegbe ti won ti wa, pelu gbogbo awon eniyan agbaye, Mo so pe: Eyin nikan ni e le pinnu lorii boya Ajo Isokan Agbaye le koju ojuse won.

**Kofi Annan**
Akowe Gbogbo-gboo
Ajo Isokan Agbaye.

Igbimo Gbogbo-gboo Fowo si awon Agbejade wonyii:

## AGBEJADE AJO ISOKAN AGBAYE LODUN MILINIONU

## 1. IGBE-LEWON ATI AWON OHUN ILEPA

1. Awa Olori Ilu ati Ijoba, pejo si Olu-ile Ise Ajo Isokan Agbaye ni ilu New York lati ojo kefa si ojo kejo osu kesan odun 2000, ni ibere Ajodun Milinionu tuntun lati fenu ko lori igbagbo wa ninu Ajo yii ati awon ipinnu re ti o je gbongbo fun itesiwaju ati alaafia ooro ati idajo ododo lagbaye.

2. A gba wi pe ni afikun ojuse enikookan wa si awon eniyan wa lagbegbe wa, a tun ni ajosepo ojuse lati gbe ogo omo eda laruge, sise ohun gbogbo ni dogba-n-dogba ati ipin olori-ko-jori ni kaakiri agbaye. Gege bi Olori, a ni ojuse pataki lati se fun awon eniyan agbaye paapaa julo awon ti o ku die kaa to fun lawujo, ni pataki awon ogo weere lagbaye ti won ni ojo iwaju.

3. A tun tenu mo sise ojuse wa lori awon idi pataki ohun ti Ajo n lepa ninu Ipinnu won ti won n fi tokantokan se lai kaare lagbaye. Lai se iye meji, Ajo yii ti fi han gbogbo aye pe won ko kere lorii bi awon Orile - ede ati awon eniyan won se n wonu ara won pelu atilehin ara won.

4. A ti gbaradi lati fidi idajo ododo rinle sinsin, ki alaafia si joko pese ni kaakiri agbaye labe ilana ojuse ati Ipinnu Ajo yii. A ti setan lati gbaruku ti akitiyan lori ominira Orile-ede gbogbo, bibowo fun aabo agbegbe won ati ominira lori eto iselu won pelu pipana aawo ni pele putu labe ilana eto idajo ati ofin agbaye. Eto awon eniyan lati da duro labe ijoba ajegaba lori eni, lai da si oro abele

orile-ede kan lona aito, ibowo fun eto omo eda ati ominira eto omo eniyan lawujo. Ibowo fun eto ni dogba-n-dogba fun gbogbo-gboo lai ya enikeni soto lori Eya, jije okunrin tabi obinrin, ede tabi esin ati ifowo-sowopo lagbaye fun yiyanju aawo ati isoro ti o le su yo lori ooro ati oro-aje , awon ohun amuludun, asa ibile ati isesi omo eda lawujo.

5. A ni igbagbo pe, koko isoro ti o doju ko wa loni ni lati rii daju pe a lo anfaani ayelu-jara lona ti yo wulo fun awon eniyan agbaye. Bi aye ti lu jara to yii, sibesibe awon anfaani re lasiko yii ko dogba ti inawo re ko si ri bakānnaa. A rii pe awon Orile-ede ti o sese n dide ati awon*yi ti oro aje won ko gbooro n koju awon koko isoro yii. Lori e, aya fi ti a ba ni afikun ninu akitiyan abasepo lojo iwaju lori awon ohun ti o da wa po gege bi omo eniyan nikan ni o le je ki ayelu-jara ni itumo. Lara akitiyan yii ni a ti ri agbekale awon ilana igbese isakoso ni kaa kiri agbaye ti yo wa ni ibamu lori eto idagbasoke awon orile-ede kookan pelu oro aje won.

6. A se agbeyewo awon igbese kan, ti won je ko see mani ninu ajosepo lagbaye ni senturi kokan-le-logun . Awon niwonyii:

- **Ominira:** Awon okunrin ati obinrin ni eto igbe aye won ki won si je abiamo ti o wuyi lai si ebi ati ifoya rogbodiyan, jije gaba lori eni tabi idajo abosi (eke). Ijoba tiwa-n-tiwa ati ijoba ti awon eniyan n kopa ninu e lori ohun ti won ba n fe, nikan lo le fi ese awon eto wonyii rinle.

- **Ori-kojori:** Gbogbo eniyan ati orile-ede kookan lo ni eto anfaani si eto idagbasoke, a ko si gbodo fi eto yii dun won. Bakannaa ni eto ni dogba-n-dogba ati anfaani fun awon obinrin ati okunrin

gbodo te won lowo.

- **Akorijopo:** Eto mimu aye lu jara won gbodo kari aye labe ilana ori ko jori ninu eto inawo re. A tun gbodo gbaruku ti awon ti ko i ti ni anfaani yii tabi awon ti o ku die kaa to fun, gba iranlowo lowo awon ti o ti gun oke agba.

- **Ifarada:** Gbogbo omo eda gbodo bowo fun ara won ninu gbogbo igbese ati isesi won ninu igbagbo enikookan lori asa ati ede.Ede ai yede, aigbo ara eni ye laarin egbe ati ogba ko gbodo da iberu tabi ijegaba lori eni sile, sugbon ki je eyi ti a gbodo mu gege bi anfaani ti o wulo ju fun omo eda. A gbodo tera mo asa wiwa alaafia, irepo ati ifikun-lu-kun lori aawo yowu ti o le je yo.

- **Ibowo fun iseda:** A gbodo rii pe a se itoju awon ohun alumoni ati iseda aye lona ti o wuyi fun idagbasoke. Nipase ilana yii nikan ni awon ohun isura ti iseda pese fun wa fi le wulo lati pese awon ohun ooro ti a le toju fun ojo iwaju awon iran ti o n bo. Bakannaa ni a gbodo se atungbeyewo awon ona ti a fi n gbe awon oja ise okowo jade fun anfaani ojo iwaju awon iran ti n bo.

- **Ajopin ojuse:** Gbogbo orile-ede ti o wa lagbaye gbodo sowopo ninu ojuse won fun igbelaruge eto oro-aje agbaye ati idagbasoke awon ohun amuludun pelu didojuko wiwa alaafia, irepo ati ajumosepo eto aabo ti o nipon laarin ara won. Lori e Ajo Isokan Agbaye ni ipa pataki lati ko gege bi egbe kan ti o so gbogbo orile-ede agbaye po.

Ki a le to pinpin awon igbese wonyii ti yo fi di amuse, ati fi idi pataki awon ohun ti a n lepa lele.

## II. ALAAFIA, AABO ATI ILO AWON OHUN OSE OGUN

8. A ko ni jawo akitiyan wa lati gba awon eniyan la ninu ogun, boya ni orile ede kan tabi laarin orile-ede kan si ikeji, eyi ti ogooro eniyan ti o le ni milionu marun ti padanu emi won laarin odun mewa sehin. Bakannaa ni a o tun gbiyanju lati gbogun ti ilo awon ohun ose apani run loju ogun.

9. A wa fenuko:

- Lati fi kun agbara ilana ibowo fun ilo ofin lagbaye ati lawujo kookan ati lati rii daju pe awon orile-ede to je omo egbe n tele ipinnu ati idajo Ile-Ejo Agbaye gege bi o ti se wa ninu akosile Ipinnu Ajo Isokan Agbaye lori ejo yowu ti o ba kan enikookan won.

- Lati le je ki Ajo Isokan Agbaye tun te siwaju ninu ojuse won lori ifeserinle alaafia ati idaabobo nipa pipese awon ohun amulo sise ti won fi le pana ote ati rogbodiyan ti o ba fe suyo, pipana aawo, eto-ilaja ati atungbe dide awon ohun ti ogun ti baje. Lori eyi a sakiyesi abo iwadi igbimo ti Ajo Isokan Agbaye gbe dide lori eto ilaja, eyi ti a fi ke si ijoko Igbimo Gbogbo-gboo lati se agbeyewo abo naa ni kiamosa.

- Lati fi kun akitiyan ifowo-sowopo laarin Ajo Isokan Agbaye ati awon egbe elekun-jekun labe ilana apa kejo (Chapter VIII) ninu akosile Ipinnu (Charter) Ajo.

- Lati rii daju pe gbogbo omo egbe n tele ilana

awon ofin ti won jijo fowo si, bii ilana ofin ti o ro mo ilo ohun ose ati awon ohun ija ogun, ofin ibowo fun omo eda lagbaye ati ofin eto omo eniyan lawujo. Ki a tun kesi gbogbo awon orile-ede lati se agbeyewo ifowosi ati kikowo bo ilana ofin ti o ro mo iwa arufin ni kootu agbaye eyi ti won fi lole ni ilu Roomu (Rome).

- Lati yara sise lori awon amookun jagun da rugudu sile lagbaye, ki won si tete fowosi gbogbo abajade akosile ipade lori awon iru isele bayi.

- Lati fi kun akitiyan wa lori gbogbgo ona fun gbigbogun ti isoro egbo igi oloro.

- Lati fi kun akitiyan wa lati fi opin si iwa odaran lagbaye paapaa julo iwa lilu jibiti owo ati gbigbe eniyan salo lati fi beere fun owo tabi nnkan miiran pelu kiko owo wolu lona ti o lodi si ofin.

- Lati wa ona iderun fun gbgbo awon ti ilana ofin fifi oro-aje bani ja ti Ajo Isokan Agbaye ba gbe jade lori orile-ede kan ti ko fi ni kan ogooro awon eniyan ti ko mowo-mese, nipase agbeyewo iru ofin bee ti ko fi ni kan iko keta lori iru oro yii.

- Lati sakitiyan ni gbogbo ona lati pana ilo awon ohun ise oloro fun ijagun. Ki a si wa gbogbgo ona miiran lati fi ropo ilo awon ohun ose yii paapaa julo lori pipe ipade agbaye lati fi pana ewu awon ohun ija oloro.

- Lati sakitiyan lori fifi opin si kiko ohun ija ogun kekeke ati awon ohun ose miiran wolu lona aito, nipase fifi ofin de kiko iru oja bee wolu lona eburu.

labe ilana awon abadofin ti o fe waye nibi ipade Ajo Isokan Agbaye ti o n bo lori isowo oja okunkun awon ohun ija ogun.

- Lati yara kesi gbogbo orile-ede lati se agbeyewo ilodi si ilo awon ohun ija ogun, kiko won pamo ati fifi won sowo sile okeere pelu kiko won danu ati atunse lori ilana yii nibi ijoko ipade lori oro yii.

10. A ro gbogbo awon orile-ede ti o je omo egbe lati bowo fun adeun ajosepo ere idaraya agbaye ni okookan, ati lapapo nisinsinyii ati ni ojo iwaju. Ki won si gbaruku ti igbimo eleto ere idaraya lagbaye lori akitiyan won lati fi ese alaafia rinle sinsin pelu gbigbo ara eni ye labe eto ere idaraya ati ti agbajo agbaye ti a mo si olinpiiki (Olympic).

## III. ETO IDAGBASOKE ATI SISO AYE DERUN

11. A ko ni kaare lati wa igbe aye ti o rorun fun tokunrin, tobinrin ati awon omode ti iya, ise ati osi ti wo lewu eyi ti o le ni bilioonu kan awon eniyan ti o wa ninu igbekun airije, airimu ati airina lawujo bayii. A ti setan lati gbaruku ti eto idagbasoke labe eto omo eda ki won fi le bo ninu ise ati osi lawujo won.

12. A ti fenuko bayii lati wa gbogbo ona lorii mimu aye derun fun gbogbo-gboo lorile-ede kookan ati lagbaye ati lati mu aye rorun fun mekunnu.

13. Aseyori lori awon ilana yi wa lowo ijoba rere ni orile-ede kookan. Bakannaa ni ijoba rere se pataki ninu isakoso agbaye, lori ihuwasi eda ninu eto inawo, owona ati isowo sowo. A ti setan lati gbaruku ti ise okowo, tita ati rira

lona ti o muna doko lai ya eya kankan soto.

14. A ti setan lati gbogun ti awon isoro ti o n koju awon orile-ede ti o sese n dide lori aito owona lati fi sise okowo ati idagbasoke v. ›n. A o wa sakitiyan lati rii daju pe aseyori suyo nibi ... se ijoko lori eto inawo fun idagbasoke ni kaakiri orile-ede ati lagbaye ti yo waye ninu odun 2001.

15. A tun ti fenuko lati wa ojutuu si awon koko ohun pataki ti awon orile-ede ti o sese n dide n fe. Lori-e, ati fowo si Ipade keta Ajo Isokan Agbaye lori awon orile-ede ti ko tii gberi ti yo waye ninu osu karun odun 2001 (May 2001). Bakannaa ni a o tun se akitiyan lati rii pe ipade naa yori si rere. A wa kesi gbogbo awon orile-ede onise okowo nlanla:

- Lati fowo si ilana fifagile sisan owo ibode ati gbigba iwe ibode lofee lori awon ti awon orile-ede akuse ba n ko jade lo si ile okeere ni saa ipade naa.
  Lati fowo si ilana eto aforijin lori sisan gbese awon akuse orile-ede ti gbese ti wo lorun ni kiamosa ati lati gba lati fagile gbogbo gbese ti awon orile-ede naa ba je lorii bi won ba ti se tewon si ninu igbese eto won lati mu aye derun fun awon eniyan won; ati

- Lati fi tinutinu se iranlowo ise idagbasoke fun gbogbo awon orile-ede ti won ba n sakitiyan lati le ise wogbo tabi din osi ku lawujo won.

16. A tun ti pinnu lati koju isoro gbese ti awon orile-ede ti o n tiraka lati dide je labe ilana eto sisun gbese won siwaju lorile-ede kan ati lagbaye.

17. A tun fenuko lati sise lori awon ohun ti o se pataki fun iranlowo awon orile-ede erekusu ti o sese n dide nipa fifi owo si Akanse eto Amuse-se ti Barbados ati abajade ijoko keji-le-logun igbimo Gbogbo-gboo lakotan ni kiamosa. A wa ro awon orile-ede agbaye lati rii daju pe won ko koyan awon orile-ede erekusu kekeke ti o sese n dide kere labe eto idagbasoke.

18. A mo riri awon isoro ati koko ohun ti o je awon orile-ede ti o sese n dide logun, nitori idi eyi a ro gbogbo awon onigbowo fun awon orile-ede wonyii lati fi kun atilehin iranlowo owo ati ilo ero ti won n pese fun won; ki won fi le jagunmolu ninu eto idagbasoke won ati lati se atilehin fun ninu irinna.

19. A tun fenuko siwajusii pe:

- Ki o to di odun 2015,ki iye awon ti o n gba Dola ($ 1) lojumo ati iye awon eniyan ti ebi n pa lawujo pelu iye awon eniyan ti ko ri omi gidi ti o mo gaa- ra mu lawujo dinku si idaji lasiko yii kannaa.

- Lati rii daju pe lasiko yi kannaa gbogbo awon omode lokunrin ati lobinrin nibikibi gbodo le pari ile-iwe alakobere ki won si ni eto kannaa labe ilana eto eko.

- Lasiko yi kannaa, ki isoro ikunle abiyamo, (iyen awon aboyun ti o n ku lasiko rirobi tabi lehin bibimo) ati bi awon ogo weere se n ku dinku si ida meta ninu merin ati ida meji ninu meta lori isele ti o wa bayi.

- Lati pana ati lati dawo itankale arun Eedi (HIV

AIDS) ku pelu arun iba lonsiriisi ati ogooro awon arun olokan-o-jokan ti o koju omo eda.

- Lati se iran lowo ti o peye fun awon omo ko ni baba ko ni iya latori arun Eedi (HIV/AIDS).

- Ki o to di odun 2020, ki a ti ni aseyori ninu igbe aye alaafia fun oke lona egberun marun (Milioonu marun) eniyan ti won ngbe ninu abete labe ilana akanse eto ti a pe ni "Ilu ti ko ni abete"

20. A tun panupo:

- Lati se eto dogba-n-dogba ati igbelaruge awon obinrin lawujo ati lati pana ise ati osi, ebi ati arun fun ise idagbasoke ti o ye kooro.

- Lati se eto idagbasoke pelu ogbon ati laakaye fun pipese anfaani ojulowo ise fun awon odo.
- Lati se atilehin ati amoriya fun awon ibi-ise okowo egboogi ki won fi le maa pese awon egboogi koseemani ni yanturu, lowo-pooku ati larowoto awon eniyan ti o nilo won ni kaakiri awon orile-ede ti o sese n dide.

- Lati se akitiyan ifowosowopo pelu awon onise Adani lawujo ati awon egbe Amuludun fun ise idagbasoke ati mimu aye derun lakotun.

- Ki a rii daju pe anfaani imo ilo ero ati gbogbo-n-se paapaa julo ninu eto iroyin ati ifohun-ranse wa larowoto gbogbo-gboo labe ilan aba ti o jeyo ninu Igbimo Alase (ECOSOC) 2000.

21. A ko gbodo kaare ninu akitiyan wa lati gba omo eda paapaa julo awon omo ati omo-omo wa la ninu ewu aibikita ilokulo omo eniyan ti a fi ba aye je ti awon ohun isura fi di aito lo lawujo.

22. A tun so asodani-loju, atilehin ti a ni fun ilana eto itesiwaju, pelu awon eyi ti a te jade ninu Ajenda kokanle-logun ti won fowo si nibi ipade Ajo Isokan Agbaye lori eto idagbasoke ayika.

23. A panupo gba wipe ti a ba fowo si gbogbo ilana igbese lori ayika wa, lona akotun lori ojuse wa, a gba pe a gbodo:

- Se akitiyan lati rii daju pe amuse ise ilana akojopo Kyoto, waye, lasiko ajodun kewa ipade Ajo Isokan Agbaye lori eto idagbasoke ayika ti yo waye ninu odun 2002, ati lati yago fun eemi eefin ti o n tu jade lati inu ile.

- Lati gbarajo fi kun akitiyan wa lori isakoso, itoju ati itesiwaju eto idagbasoke awon ile-igbo.

- Lati fi gbogbo ara sise lori agbejade abo ipade imugbooro imo nipa eda, gbigbogun ti itankale ogbele (Airo ojo) ni awon orile-ede ti iyan n ba ja ati awon agbegbe asale ni ile Afirika (Africa).

- Lati mu ki imu gbooro ba wiwa orisun omi nipase eto isakoso omi ni elekun-jekun lorile-ede kookan ati ni ijoba ibile; ki ipese omi fi le to fun lilo ti ko fi ni gbe.

- Lati fi kun akitiyan ifowosowopo lati din isele

jamba ojiji ati awon eyi ti o je afowofa ku.

- Lati rii daju pe iroyin nipa ilosi eda lorile aye ati imisi ile wa larowoto gbogbo mutu muwa.

## V. AWON ETO OMO-EDA OMINIRA TIWA-N-TIWA ATI IJOBA RERE

24. A ko ni sinmi lori akitiyan lati wa ominira tiwa-n-tiwa ati imugbooro ilana ofin pelu ibowo fun gbogbo eto omo eda ni kaakiri agbaye ati ominira ti ara eni ninu eyi ti a ti ri eto lati te siwaju.

25. Nitorina an a panupo :

- Lati fi gbogbo ara bowo fun eto omo eda lagbaye.

- Lati gbiyanju lori aabo ati wiwa ilosiwaju ninu isesi eda, eto iselu, eto oro-aje, awon ohun amuludun ati eto asa ibile fun gbogbo-gboo.

- Lati fi kun agbara awon orile-ede ki won fi le muse se lori igbese eto iselu ati ibowo fun eto omo-eda pelu eto awon ko to nnkan lawujo.

- Lati gbogun ti gbogbo ona idasile isele rogbodiyan ti o le lodi si awon obinrin ati lati fowo si abo ipade lori yiya obinrin soto lori ohun kohun.

- Lati gbe igbese ti yo rii daju pe ibowo wa fun eto awon ti o n lo lati orile-ede kan si omiiran, iru awon osise bee ati ebi won. Lati

fi opin si iwa eleyameya lawujo ati lati wa ibagbe po pelu ifarada ati igbora-eni ye yekeyeke.

- Lati jumo sise po fun aseyori eto oselu ki gbogbo-gboo ni anfaani lati kopa ni kaakiri awon orile-ede wa.

- Lati rii daju pe ominira wa fun awon oniroyin lati le sise won ati eto awon ara ilu lati mo ohun ti o n lo lawujo.

## VI. IDAABOBO LOWO EWU

26. A o se akitiyan lati rii daju pe a se iranlowo ati idaabobo ti o peye fun gbogbo awon omode ati awon eniyan ilu ti won ba se agbako jamba ojiji, isele ogun ati ifipa je gaba lori eni, ki won fi le ni anfaani lati gbe igbe aye alaafia ni kiakia.
A wa fi ohun sokan:

- Lati se imugbooro ati afikun idaabobo awon ara ilu lasiko isele pajawiri labe ilana ofin idaabobo eto omo eniyan lagbaye.

- Lati fi kun eto ilana ifowo-sowopo lagbaye pelu ajumosepo atilehin iranlowo fun omo eda ni awon orile-ede ti won ba gba awon Atipo lalejo. Ati lati se iranlowo lori bi won yo se pada si ilu ni alaafia ki won si darapo mo awon eniyan won lai si wahala.

- Lati gbaruku ti fifi owo si ati imuse se abajade ipade Eto awon Omode ati aabo omode lasiko ogun ati tita awon omode bi eru, fifi won se ise asewo ati lilo aworan won lona abuku.

## VII KIKOJU OSUNWON AWON KOKO OHUN TI O N JE AFIRIKA LOGUN

27. A o se atilehin fun ifese rinle ijoba tiwa-n-tiwa ni ile Afirika pelu iranlowo fun awon eniyan re lori iyanju won lati wa alaafia, lile osi wogbo ati ilosiwaju ninu eto idagbasoke ki ile Afirika fi le peju pese ninu eto oro-aje agbaye.

28. Nitori idi eyi a fi enu ko:

- Lati se iranlowo lori ilana eto oselu ati eto akoso ijoba tiwa-n-tiwa ni awon orile-ede ti o sese n dide ni ile Afirika.

- Lati gbaruku ti ilana eto didena isele rogbodiyan, ede aiyede ki ilosiwaju fi le de ba isakoso ti yo ni ifokanbale lati le mojuto awon ohun ti yo je ki wiwa alaafia gberu sii ni ile naa.

- Lati muse se lorii mimu aye derun lawujo ki ilosiwaju le gberu sii ni ile Afirika. Lori e ni igbese lati fagi le gbese agbelaruge oja, iranlowo lori ise idagbasoke, gbigba awon ara okeere laye lati da ise sile ati ifaaye gba imo ise ilo ero igbalode.

- Lati ran ile Afirika lowo ki won fi le lagbara lati gbogun ti arun Eedi (HIV/AIDS) ati awon arun miiran ti o n pani lawujo.

## VIII. SISO AGBARA AJO ISOKAN AGBAYE DOTUN

29. A ko ni kaare lati le je ki Ajo Isokan Agbaye je orisun ti o le kapa gbogbo awon ohun ti a n lepa wonyii: Jija fun

ilosiwaju gbogbo eniyan agbaye, gbigbogun ti osi lawujio eniyan ati lile aimokan ati arun wogbo. Igbogun ti aisododo ninu idajo, igbogun ti rogbodiyan, rukerudo ote ati tembelekun, pelu gbigbogun ti ifasehin ati iparun alajobi wa.

30. A wa gba pe:

- A ni lati fi ipo igbimo ipade Gbogbo-gboo si ipo agba ti yo maa dari ilana eto iselu ati asoju Ajo Isokan Agbaye ki o le ni aseyori ise.

- Lati fi kun akitiyan wa lati se atungbeyewo Igbimo Eleto Aabo ninu gbogbo ojuse re.

- Lati tubo fun igbimo Eleto oro-aje ati Amuludun lagbara sii lori aseyori re ki ojuse re le ni ipa pataki gege bi o ti se wa ninu Ipinnu Ajo.

- Lati fi agbara kun ojuse Ile-Ejo Agbaye lati le rii daju pe idajo ododo ati ilana ofin agbaye gberu sii.

- Lati se atilehin fun ajosepo ati ifowosowopo awon eka Ajo Isokan Agbaye labe ojuse won.

- Lati rii daju pe apese awon ohun eelo amuseya fun Ajo yii lati le fi sise won lasepe.

- Lati ro Olu Ile-Ise Ajo ki o lo awon ohun eelo ti o wa larowo to re lona ti o boju mu labe ofin ati ilana ti Igbimo Gbogbo-gboo fowo si fun anfaani gbogbo omo egbe nipase lilo eto akoso ti o ye kooro ati ilo ero. Ki won si tera mo awon

ojuse won ti o wa ni ibamu pelu awon ohun ti o je omo egbe logun.

- Lati gbaruku ti ilana eto aabo fun Ajo Isokan Agbaye ati awon osise won.

- Lati rii daju pe won tele ilana ifowosowopo pelu gbogbo eka Ajo Isokan Agbaye ati awon asoju won fun aseyori ninu kikapa isoro ti o le koju eto idagba soke ati alaafia.

- Lati fi kun akitiyan lori ajosepo laarin Ajo Isokan Agbaye ati awon ile Igbimo Asofin pelu awon asoju miiran bii Alaafia, Aabo, Eto oro-aje ati idagbasoke awon ohun amuludun, ofin agbaye, eto omo eniyan, ominira tiwa-n-tiwa ati awon koko oro ti o ba jemo okunrin ati obinrin.

- Lati fun awon onise Adani, awon egbe alajumosepo ati egbe ilu ni anfaani ti o bu yaari ki won fi le kopa ninu ojuse Ajo fun aseyori ise won.

31 A ke si Igbimo Gbogbo-gboo lati maa se atungbeyewo awon atejade yii loore-koore lori igbese ti won ba ti gbe lati mu ise yii se.

32. A wa parapo tun fenuko lojo male-gbagbe yii pe Ajo Isokan Agbaye je orisun ile fun gbogbo ebi omo eda labe eyi ti a o maa mu omi ninu amu alaafia, ifowosowopo ati idagbasoke. Nitori naa, a wa je jee atilehin fun ohun kan naa ti a n lepa pelu ipinnu wa lati se aseyori.

Resolution A/RES/55/2
8 September 2000

**AWA ENIYAN**
**IPA TI AJO ISOKAN ORILE AGBAYE**
**KO NI IJU**
**SENTURI - KOKAN-LE-LOGUN**

# 2

**IJABO AKOWE GBOGBO-GBOO**
**FUN IJOKO IGBIMO AJO**
**ISOKAN ORILE-EDE AGBAYE NINU**
**MILINIONU YII**
**NI SOKI**

*2000*
*AJO ISOKAN AGBAYE*

**AWA ENIYAN**

**IPA TI AJO ISOKAN**

**ORILE-EDE AGBAYE**

**KO NINU**

**SENTURI KOKAN-LE-LOGUN**

Pelu aridaju pe ninu senturi yii,"Oye ki o je asiko igbaradi isokan lori ireti rere fun Ajo Isokan Agbaye laarin igba tuntun yii" Igbimo gbogbo-gboo Ajo Agbaye pinnu ninu osu kejila odun 1998 lati jeki ijoko won

karun-le-laadota ti yo bere lojo karun osu kesan odun 2000, je eyi ti won yo pe ni Ijoko Igbimo apapo Ajo Isokan Orile-ede Agbaye ninu Milinionu yii. Bakanna ni won tun pinnu lati pe ijoko ipade Milinionu ti yo waye lati ojo kefa si ojo kejo osu kesan odun 2000.

Fun ipalemo ijoko ipade naa, eyi ti a lero pe yo gbooro ju gbogbo ipade to ti waye ri lo, pelu agbajo awon Olori Orile-Ede tabi awon olori ijoba ti won yo pese sibe. Lori e ni Akowe gbogbo-gboo Ajo Isokan Orile-ede Agbaye Kofi Annan fi se ifilole ijabo re ninu Milinionu yi lojo keta osu kerin odun 2000.

Akole ijabo naa lo bayii, " A wa eniyan: Ipa ti Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye ko ninu Senturi kokan-le-logun". Ti o si se agbekale eto amuse-se fun gbogbo eniyan ni kaakiri agbaye. Lara awon koko ilana igbese ti Ajo Isokan Orile-ede Agbaye n la kaka lati se laarin odun marun-le-laadota sehin lati ri aimoye akanle-se eto lori awon ohun ti won n lepa eyi ti akowe gbogbo-gboo Ajo yi fi n kesi awon Olori ni kaakiri agbaye lati gbe yewo. Awon ohun wonyi ni a kojo po ni soki ni isale iwe yii.

**SENTURI TUNTUN, ERO TUNTUN**

Asiko senturi tuntun ati ijoko ipade senturi yii, je anfaani nla fun gbogbo eniyan

agbaye lati foju inu wo pataki awon ohun to so won po ati ohun

ti won n lepa, eyi ti o jeki ajosepo won fese rinle ju ti atehin-wa lo. Won ni ireti ninu awon asiwaju won lati se agbeyewo awon ohun ti o je won logun fun ojo iwaju. Ajo Isokan Orile-ede agbaye ni agbara lati koju awon isoro to wa niwaju won, ti gbogbo awon omo egbe ba ni ero kanna lori ohun ti won n lepa. Nigba ti a fi Ajo Isokan Orile-ede Agbaye lele ninu odun 1945 lori ajosepo ni kaakiri agbaye, Ajo yii ti se aseyori ni awon agbegbe kan. Anfaani ti wa suyo bayi lati se atun gbe dide Ajo Orile-ede Agbaye ki won fi le tun igbesi aye omo eda se lawujo ninu saa milinionu tuntun yii.

## GBAJO AGBAYE ATI ISAKOSO IJOBA

Anfaani ti o wa ninu agbajo agbaye kii se kekere; imugboro eto idagbasoke, igbe aye rere, ati awon anfaani to n suyo lakotun. Sibesibe awon anfaani wonyi ko dogba ni kaakiri agbaye nitori pe ifowo sowopo agbaye ko i tii duro soju kan labe ofin ipin okowo alajosepo.

Ninu odun 1945, awon oludasile Ajo yi da ajo alajosepo sile fun ajumo sepo lagbaye. Eto yi sise fun ajumo-sepo lagbaye. Eto yi sise, ti o si jeki agbajo agbaye dide. Ayorisi yi lo jeki abasepo lagbaye lu jara won. Lori e ni awon asiwaju ni kaakiri agbaye fi gbodo ta kiji lori awon ohun ti won n lepa loni.

Ni ode aye tuntun ti a wa bayi, ogooro awon egbe, ati awon eniyan kookan lawujo ni won ti n jumo sowopo fun wiwa ifowo-sowopo laarin ara won lai lowo ijoba ninu. Ilana agbejade amulo awon ero igbalode(tekinoloji) tun mu aye rorun fun anfaani gbigbo ra eni ye yekeyeke lori awon ohun ti won n jumo n lepa. Sugbon sa ewu n be loko longe, beeni longe funra re ewu ni. Iwa jibiti, odaran lilo egboogi oloro, iwa adigun-kogun, adalu-dapo, ooru inu afefe, arun kogboogun, ilo awon ohun ose ogun, awon

ti ogun le kuro nilu ati awon atipo gbogbo wonyi lo kari aye ju bo ti wa tele lo. Eru n ba awon eniyan lori iroyin olokan-o-jokan to buru jai ti won n gbo lagbaye. Bakanna ni okan awon eniyan ko bale lori isele ifipa je gaba lori eni, idajo oni-kumo ati ifiya jeni lona aito ti o gbode ni awon orile-ede ile okeere pelu ireti pe awon ijoba orile-ede naa a wojutu si awon isele wonyi. Bi a ba fe ajumo sepo agbaye to ye kooro ti a si fe lati yago fun awon isele buruku, o di dandan lati seeto ijoba to gbamuse ati lati wa gbogbo ona iselu alajosepo.

Eyi ko ja si pe a n fe ki ijoba agbaye waye tabi pe ki a fopin si iduro awon orile-ede kookan,sugbon ki a wa ona ti awon orile-ede yo fi ni Akotun agbara. Ti won yo si ni anfaani lati se atilehin agbara laarin ara won lori ipinnu kanna nipase ajose isakoso. Won agodo gba pe igba n yi, ki won si duro lori ifo wo-sowopo pelu awon ajo miiran ati ti alajosepo lagbaye.

*"Bi o tile je pe isokan awon Orile-ede agbaye je Ajo awon Orile-ede, a ko Ipinu won ni oruko 'Awa Eniyan'*

*......... fun idi eyi Ajo isokan Agbaye gbodo duro fun igbaruku ti awon nnkan to je anfaani ati ireti fun awon eniyan nibikibi"*

Ni gbogbo ona ni won gbodo gbiyanju lati gbe awon ilana ti yo rorun fun won kale lorii bi awon nnkan see n yi lagbaye.

A i dogba awon ohun isura lode oni lagbaye, ipo ise ati osi ti ogooro awon eniyan wa, edeaiye-de to gbode kan ati adalu ooru afefe,

gbogbo awon nnkan wonyi ni ko jeki eto idagbasoke gbooro sii,

ayafi ti adehun ajumosepo ba le jeyo. Akanse eto iforo wani lenu wo lowo awon ara ilu ni kaakiri ile mefa lagbaye fiyeni pe, igbese yi gan an ni awon eniyan fara

## RIRI-JE ATI RIRI-MU PELU IRORUN: ILANA ETO IDAGBASOKE

Opo ere lo ti jeyo ninu oro-aje laarin aadota odun sehin. Sugbon o le ni bilioonu kan awon eniyan ti ireti won ko ti i to dola kan lojumo. Agbajo ise ati osi ti o wa lawujo ni kaakiri awon orile-ede ko dogba, koda laarin won papaa o je isoro nla ti o koju omo eda. Bakanna ni o tun jeki opo awon isoro miiran to buru jai pelu rogbodiyan olokan-o-jokan maa suyo lairo tele. Bee si ni awon eniyan tun n po sii yanturu lagbaye, ti o je wi pe awon orile-ede to talaka ni won poju si. Bi a se n po sii ni agbaye pelu ise ati osi ti o n wo awon eniyan lorun je koko isoro ti o koju enikookan wa. A ko gbodo kuna lati koju isoro yii.

## A TI RO AWON OLORI ATI ASIWAJU IJOBA LATI GBE AWON IGBESE WONYII

**Airina tabi Titosi:** Lati rii daju pe ninu odun 2015, iye awon eniyan – lagbaye din si ilaji iko meji-le-logun ninu ogorun ogooro awon eniyan ti won n gba owo ti ko to Dola kan lojumo.

**Omi:** Lati rii daju pe iye awon eniyan ti won ko ni anfaani si omi to see mu dinku se iye won to wa bayi (ti o je iko kan ninu marun) ki o to di odun 2015.

**Imo Eko**: Lati rii pe aala ti o wa laarin tako tabo ninu gbigba eko ni ile- iwe alakobere ati ile-eko giga dinku ninu odun

2015, ati lati rii daju pe ki o to di odun 2015, gbogbo awon omode ni won pari imo eko won ni ile-iwe alakobere.

**Ilera ati Arun Kogboogun (HIV/AIDS):** Ki a rii pe a dekun itankale arun ko gboogun Eedi (HIV/AIDS) ki o to di odun 2015 nipase igbese wonyi:

- Fifowo si ilana igbese lati wa ona adinku arun ko gboogun laarin awon omo odun meedogun si merin-le-logun lona ida merin ni kaakiri awon orile-ede ti arun naa po si ki o to di odun 2005. Ki arun naa si tun dinku ni ida merin ni kaakiri agbaye ki o to di odun 2010.

- Dida asiko fun idaabobo lowo arun yi, lati fi polongo ilaniloye fun awon odo-kunrin ati awon obinrin lori awon ona ti won fi le yago fun arun ko gboogun yi o kere tan ida-mesan ninu mewa ki o to di odun 2005 ati ida mokan-din-logun ninu ogun ninu odun 2010, o kere tan
- Fun gbogbo awon orile-ede ti arun yi poju si, ki won ni akanse ilana eto lori e laarin odun kan lehin ijoko igbimo yii.

Orisi-risi iwadi gbodo tun waye lori isoro to koju eto ilera ni kaakiri awon orile-ede to fere to ida mesan ninu mewa awon eniyan to wa lagbaye, bii arun iba, iko egbe, otutu aya ati arun igbe gbuuru

**Agbega awon adugbo rada-rada:** _Lati fowo si ati lati gbe igbese "kiko awon ilu olaju" Eyi ti Banki agbaye ati Ajo Isokan

Agbaye fi lole fun ilosiwaju agbega ati igbe aye rere opo awon eniyan bii agorun milionu ki o to di odun 2020.

**Kiko Afara Ayelu-jara** – Lati se a tungbeyewo awon ilana isakoso lori eto inawo ero amaye-lujara won lati rii daju pe awon eniyan ko padanu anfaani lilo awon ohun eelo ero yii.

**AKANLE RO AWON ORILE-EDE TO TI DIDE PE: KI WON NI:**

**Ifaye-gba Ise Okowo:** Ki awon orile-ede to ti dide fi aye gba kiko oja awon orile-ede to ku die kaa to fun wolu won. Ki won si gbara di lati fowo si ilana kiko oja wole lai sanwo ibode fun gbogbo awon oja ko se ma ni lati awon Orile-ede to ti gbegba oroke labe ilana ipade Ajo Isokan Agbaye ni osu keta odun 2001.

**Iyora Ninu Gbese**: Lati yara sise lai si idaduro kankan lori imugbooro eto aforijin gbese fun awon orile-ede kuje-kuje ti gbese ti wo lorun lori adehun ti o waye ninu odun to koja ati lati gbaradi fun fifagile gbogbo gbese ti awon Orile-ede yi ti je gege bi iwuri fun awon orile-ede ti won n gbiyanju lati pana airina, airilo ku lawujo. Lojo iwaju won gbodo gbe ilana tuntun jade ti yo fi aaye sile fun gbigbegi le gbese yowu ti awon orile-ede to sagbako jamba ojiji tabi rogbodiyan ba je. Ki won si fi ote le sisan gbese pada lori iko to ba poju ninu owo ile okeere to n wole fun won pelu idasile iko olu-petu si oro gbese jije

**SISE IRANLOWO:**

Lati faye gba sise atilehin fun ise idagbasoke, paapaa fun awon orile-ede ti won n tiraka lati din ise ku lawujo won.

*"Bi a ba fe jere awon aseyori ninu Agbajo Agbaye pelu ifarada awon alebu re, a bgodo ko nipa isako ijoba Rere ati bi oti ye ki a jomu sowopo sakoso ijoba"*

**Arun Ko-Gboogun Eedi(HIV/AIDS):**
**Lati sowopo sise pelu awon ibi-ise**
Okowo egboogi ati awon alatilehin miran lati gba abere ti yo le pana arun Eedi, ki iru egboogi yi wa larowo to awon eniyan ni awon orile-ede to sese n dide.

**Ni Ile-Afirika(Africa):** Lati pese awon koko ohun to joju fun ile Afirika lori ohun ti won n fe ati lati gbaruku ti won lori akitiyan won lati kapa awon isoro to n koju won.

**Bibo Lowo Iberu-bojo Ilana Eto Aabo:** Ikoju ogun laarin orile-ede kan si ekeji ti n kase n le. Sugbon laarin odun mewa sehin ogun abele ti ran emi to le ni milionu marun lo sorun apapa ndodo ti oke aimoye eniyan ti so ile ati ibugbe won nu. Bakanna ni awon ohun ija oloro ajenirun ti di eru jeje lawujo. Akitiyan lori idabobo to ye ki o je aabo aala ile kan lowo ota ode – ti wa a di aabo aladugbo ati enikookan lowo rogbodiyan abele. Gbogbo ona ni a gbodo fi gbogun ti rogbodiyan apanirun ni kanmo-kosa.

**Didena:** Laarin odun mewa sehin rogbodiyan wopo laarin awon orile-ede to kuse paapaa ni agbegbe ti ko si dogbandogba larin awon eya tabi isori awon elesin olokan-o-ojokan. Lati yago fun

iru isele bayi, o se pataki lati wa eto oro-aje ti yo wa ni dogba-n-dogba pelu eto fun gbogbo otokulu ati eto iselu ti iko gbogbo won yo ni asoju. Bakanna ni kiko ohun ose kiri lona to lodi sofin pelu owo ati ohun alumoni kan gbodo je ohun amojuto daadaa.

**Didaabo-bo ilana eto:** A gbodo wa gbogbo ona to jingiri lati fidi ilana ofin omo-eda lagbaye rinle sinsin ati lati fopin si ilo agbara, lona aito.

**Wahala lori pipetu soro:** Opolopo ni ominu ti n ko pe " Ipetu soro labe ilana olulaja" le je ona kan nipa kikoju bo oro oloro labe ijoba abele kan, sugbon ko si ilana ofin kankan ti a le lo lati fi boju lori ifiya jeni lona aito. Iko adigun olulaja labe ase Igbimo Eleto Aabo gbodo je igbese ikehin lehin ti gbogbo iyanju ba ti pin lori ipetu soro ti ko lojutu: sugbon ti isele ti opo eniyan ba padanu emi ba waye, o di dandan lati gbe iru igbese yii.

**Fifi agbara kun igbese ilaja:** A ti kesi igbimo ipade milinionu lati se agbeyewo awon aba ti iko igbimo alabe-sekele ti Akowe Gbogbo-gboo gbe jade lati se atunse lori gbogbo awon eka to ro mo ilaja tabi pipetu soro.

**Ilana Ifipa-muni** – Fifipa dena ise oro aje, je ilana ofin oloju kan. Ofin yi maa n fiya je awon eniyan ti ko mowo mese, koda ofin naa ko wulo lori ise ti a fi gbere kale. Awon ilana igbese tuntun gbodo jeyo lori awon ona ti a fi le maa fipa muni paapaa Igbimo Eleto Aabo.

**AWON OHUN OSE KEKE-KE** :- Akowe gbogbo-gboo ti kesi gbogbo omo egbe Ajo lati bojuto kiko ohun ija keke-ke bii-

- Gbigbe ilana to muna-doko jade lorii kiko ohun ija wolu.

- Lati se atilehin fun adinku ninu kiko ohun ose wolu lati ile-okeere, kiko won jade lo si ile-okeere ati adinku ninu sise awon ohun ija wonyi ni Iwo-Oorun ile Afirika.

- Imugbooro de awon agbegbe miiran- paapaa laarin awon orile-ede to sese jagun tan " kiko oja dipoo ohun ose"eto yi gbayi ni ile ( Mazambique) Mosambiki, Panama, El Salvador ati Albania.

**OHUN OSE OLORO:**-_A ti kesi awon omo egbe Ajo lati ji giiri si ojuse won nipa wiwa gbogbo ona lati wojutu isoro ati ewu awon ohun ija oloro pelu wiwa ona lati pe ipade agbaye lorii wiwoju-tu si pipana-an lilo ohun ija oloro.

**IRETI OJO IWAJU:- ILANA FUN ETO AYIKA**

Ni bayi, gbogbo wa ni a gbodo bojuto wiwa aabo lorii bi awon iran to n bo lojo iwaju se maa gbe igbe aye irorun lorile aye. Sugbon a kuna lati gbe igbese yi. A ti fi igbe aye awon omo wa wole lori awon nnkan ti ko bojumu. Eyi je ojuse fun gbogbo awon orile-ede to gbajumo ati awon eyi to je talaka. Ipade ti o waye ni ilu Rio ninu odun 1992 lo se agbekale ilana yi bee si ni atejade ilana ti ilu Montreal se pataki pupo. Sugbon nibi-kibi ni

a o ti kobiara si oro yi. Ki o to di odun 2002 ti Rio + 10 maa waye awon omo egbe Ajo gbodo se agbedide ijiroro, ki won gbaradi lati sise taagun-taagun lori awon koko oro yi.

**KIKAPA AYIPADA OJU-OJO:-** Abojuto gbodo waye lori agbejade eefin to n tu jade lati ile, ki a fi le din-in ku si ida meta ninu marun. Eleyi le seese bi a ba tera mo lilo awon ohun elo alagbara ti a si n wa awon ona lati so awon ona ohun elo agbara dotun. Igbese kini ni lati fowo si ilana Kyoto ti yo fi bere si ni sise ninu odun 2002, ki a si ri aridaju aseyori e.

**GBIGBOGUN TI ISORO OMI:-** Abo iwadi beere fun yiyara fowo si abajade ipade agbaye lori oro omi, eyi to kesi adinku iye awon eniyan ti ko ni anfaani lati ri omi lo lawujo ki o to di odun 2015. Bakanna ni abo ipade naa beere fun " ilana omi to mo gaara" ti yo le jeki ise ogbin gbeeru sii labe ilo omi; ti a o si seeto akoso lilo awon omi odo ati agbara lona to bojumu.

**IDAABOBO ILE OKO:-** Ona ti o dara ju lati fi le bo opo eeyan to n gberu sii lagbaye ni lati se eto idaabo fun ile ogbin labe ilana lilo awon ero igbalode, sugbon ariyanjiyan ti n waye lorii ewu to wa ninu lilo awon ohun eelo wonyi. Akowe gbogbo-gboo ti n sakitiyan lati gbe ilana isakoso kan jade ti yo le yanju isoro ti o koju wa yi lati le jeki talaka ati eni ti ebi n pa roju gbaye.

**IDAABOBO ILE IGBO ATI ILO EWEKO:-** Ni gbogbo awon agbegoe wonyi abojuto ile olora lo se pataki ju. Gbogbo awon ijoba ati awon onise adani ni won gbodo sowopo jijo sise.

**AGBELARUGE ILANA IHUWA-SI ATI IFARA-SISE**
Gbogbo eniyan pelu awon ijoba ni won gbodo kobi ara si ayipada iwa rere ati ifara sin ilu. Akowe gbogbo-gboo gbe awon ilana merin to ta koko kale fun awon orile-ede!

- Kiko awon ara ilu ni imo eko
- Fifi "ilana ogbin" lole kaakiri ayika lati gbe oro-aje laruge.
- Fifowo si awon ilana ti yo mu ise oja tita ati rira rorun laarin orile-ede kookan pelu ifowo-sowo po lori adinku owo-ori oja.
- Lati wa ilosiwaju ninu imo iwadi sayensi fun anfaani ati ilosiwaju awon ohun ti a n lepa lagbaye lasiko milinionu yii.

**ISODOTUN AJO ISOKAN ORILE-EDE AGBAYE**
Lai si Ajo isokan awon orile-ede ti o lagbara, yo je isoro pupo lati le rojutu si gbogbo awon nnkan ti won nlepa. Lati fun Ajo isokan Orile-ede agbaye lagbara sii, wa lowo gbogbo awon ijoba paapaa julo igbese won lati fowo-sowopo sise laarin ara won, awon eka Aladani, awon egbe alaanu ati awon Ajo Alajumopo sise ilu lati wa ojutu si awon isoro ti a ka sile wonyi. Ajo Isokan Agbaye gbodo je amu lati dari awon eka to ro mo won. Bakanna ni o gbodo wa awon ona ilo ero igba ode oni, paapa julo itankale iroyin labe ilana ilo ero ode oni. Akowe gbogbo-gboo gbe awon aba kan jade lori awon igbese yii.

**KI A MO IBI TI AGBARA WA DE:**

Ajo isokan Orile ede agbaye

ko gbajumonipase agbara Sugbon lati ara ilana orisun Re, nipa atilehin ati ojuse re lori isokan agbaye, gbogbo ilakaka re lati gbe awon igbese to ye lori oro agbaye pelu ifokan tan lori wiwa igbe aye rere fun awon eniyan. Agbodo tun so awon igbese yi di otun nipa titera mo pataki lile ofin, bakanna ni a tun gbodo gbaruku ti Ajo isokan agbaye nipa atunto igbimo eleto aabo ki ise re le yorisi rere. A tun gbodo se imugbooro abasepo to wa laarin Ajo Isokan Agbaye ati awon orisirisi egbe , ilu pelu awon iko Aladani ati awon ma je ki ilu baje.

*"Awon eniyan agbaye n so fun wa pe aseyori wa latehin wa ko kaju iwon, bi a ba le foju inu wo awon ohun ti a n lepa. A gbodo tera moo, ki a si see dara ju ti atehin lo"*

**AKOJOPO SOJU KAN FUN AYIPADA:** A gbodo wa gbogbo ona lati fi gbe ilana kan jade ti yo je ona ifowo-sowopo laarin iko awon orisirisi egbe ati awon ijoba fun aseyori awon ohun ti a n lepa.

**AMULO ERO IGBALODE:** A le lo awon ohun elo ero igba lode lati le jeki ise Ajo Isokan Agbaye yori si rere ki won si le ni abasepo pelu awon eka to wa kaakiri agbaye. Bi a ba fe se eleyi, a gbodo faye sile fun ayipada. Akowe gbogbo-gboo ti kesi ibi-ise okowo iroyin ilo ero, lati se iranlowo fun won lori e.

**ITESIWAJU NINU AYIPADA RERE:** Bi a ba fe kapa awon ohun ti a n lepa ninu senturi kokan-le-logun a gbodo se atungbeyewo ati atunto egbe, ki a mo koko ohun ti o je orandun fun awon omo egbe, ki a si din ayonuso ku lori eto isakoso. Ile igbimo gbogbo-gboo gbodo gbe awon ilana ifenuko won jade lori awon ilana tuntun ati lati fi eto isuna tuntun lole.

**AWON KOKO AMUSE ISE.**

Fun apeere lori ajumosepo ise, Ajo Isokan Agbaye le se agbejade sise awon koko ise merin ti Akowe gbogbo-gboo gbe kale ninu abo re.

- Iko oluranlowo ilu ti a le pe ni iko oniroyin ilo ero ode-oni tii Ajo Isokan Agbaye ("UNITeS") lati se eto ekose fun awon eniyan orile ede to sese n dide lori lilo awon ero iroyin ti igbalode (Intaneti) pelu anfaani won
- Agbo akojopo iroyin lori eto ilera ti yo ni egberun mewa ategun si kaakiri awon ile iwosan ati ile egboogi ni awon orile - ede to sese ndide, fun gbigbe iroyin lori eto ilera jade. Awon alatilehin ilana yi ni Egbe Alaanu (Web Md Foundation) Ajo eleto isokan Orile-ede Agbaye ati awon iko alajose miiran.

- Iko awon oluranlowo "Olu-gbaradi ni sepe" Awon ni yo pese ohun elo ifohun ranse fun iranlowo awon

osise ti yo lo gbemi la lasiko jamba ajalu ni awon agbegbe ti iru isele yi ba ti waya. Ibi -ise taa mo si (Ericcson Communication) pelu atilehin ajo Isokan Agbaye ati awon egbe alagbelebu pupa ati Olosupa pupa (Red Crescent) ni won yo dari iko Alaanu naa. Agbedide iko alagbo ajosepo ti yo se iwadi lori awon ona tuntun lati fi koju isoro pipese ise fun awon odo. Iko Amusese yi labe awon asiwaju Banki Agbaye ati egbe awon osise lagbaye pelu awon ile ise Adani ati awon asiwaju egbe ilu maa gbe awon aba won fun awon ijoba laarin odun kan.

**AWON ANFAANI TO SUYO:**

Ni ipari Akowe Gbogbo-gboo gbe awon koko anfaani mefa jade ti o suyo labe ilana ipinnu Ajo ti o jemo odun senturi tuntun, Ominira, pinpin dogba n-dogba ati ajosepo, ifarada, imusuuru lai da rugudu sile, ibowo fun awon ohun eda ati ajumosepo ojuse wa. O ro ipade milinionu lati fenu ko lori orisirisi aba lati inu akosile ijabo, ki anfaani ohun ti won n le pa le so eso rere.

## FOR MORE INFORMATION

On the Internet: http://www.un.org/millenium

Office of the Millennium Assembly

Department of Public Information

Room S-3275, United Nations

Room S-955, United Nations

New York, NY 100017.

New York, NY 10017

Tel: (212) 963-5739

Public queries: tel (212) 963-4475

Tel: (212) 963-0616

Media queries: tel (212) 963-6870

E-mail: millennium@un.org

NGO queries: tel (212) 963-8070

Fax: (212) 963-0536;

e-mail: inquiries@un.org

Published by the

United Nations Department of Public Information

DP1/2110 - MAY 2000 - 12M